IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,701 FRIDAY FEBRUARY 18, 1966 (2D)

## Ọkunrin Kan Ji Moto Ọba Gbe ?

IBADAN:- Gbogbo ile lo kunsọsọ ti ẹse ko si gbeji fun ogunlọgọ ọkẹ aimoye awọn enia ti nwọn wa ni ile ẹjọ kekere Ibadan nigbati awọn ọlọpa mu ọdaran kan Joseph Tutu, eni ọdun mẹrindinladọta, ti awọn ọlọpa pe ni akọwe ẹgbẹ Demọ, wa siwaju adajọ ni ẹjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣe ẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ wipe, ọdaran na ji moto Ọba C. D. Akran, No WK 308 gbe ni Molete ni ọjọ kọkanlelogun oṣu kini ọdun yi.

Ọlọpa na tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, moto ayọkẹlẹ ti ọdaran na ji gbe ati pe iye owo moto na si jẹ ẹgbẹta ponun (£600), ṣugbọn nigbati nwọn ko ri ọdaran na ni nwọn ba sọ fun awọn Ọlọpa ki nwọn to wa ri mu.

Ninu ẹjọ ti ọdaran na, eyiti o rọ, lati fi gba ara rẹ kalẹ, ọdaran na sọ niwaju adajọ pe, on ko jẹbi ẹsun na. ni adajọ ba fi ọjọ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kẹta oṣu ti mbọ yi, lori iduro irinwo ponun (£400) ati onigbọwọ iyekanna.

Bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si, ẹo tun ma a gbọ o.

# Gomina Tu Igbimọ Ọba Ka !

# AIYE OLỌWỌ FỌ !

# Ọọni Ifẹ Tun Di Alaga

IBADAN:- Ibanujẹ d'ori agba kodo ni agba yanu Irohin ti o kan gbogbo awọn enia kuu ni deede agogo mejila ọsan ana ojọ Ọjọ 'Bọ ti iṣe ojọ ketadinlogun oṣu yi jẹ fun gbogbo awọn enia nigbati awọn gbele gburo wipe Ọlọla Francis Adekunle Fajuyi, Gomina Ologun Iwọ Orun Naijiria ti tu Igbimọ awọn Ọba ati Ijoye Ipinlẹ na ka, o si ti tun yan awọn Ọba ati Ijoye miran lati tun ma a ṣe akoso Igbimọ na lọ bayi.



Ọlọla Adesọji Aderẹmi
Ọọni Ọba Ile-Ifẹ

Ṣugbọn ohun to ya gbo gbo awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun lẹnu ninu Irohin ti nwọn gbo na ni pe nigba ti Gomina na tu Igbimọ awọn Ọba na ka tan, o yan awọn ọba ati Ijoye mẹsan pe ki nwọn tun ma ṣe akoso Igbimọ na lọ.

Nigbati Gomina na yan awọn ọba ati Ijoye mẹsan na tan, o wa yan Kabiyesi Adesoji Aderẹmi Alaiyeluwa Ọọni Ọba Ile-Ifẹ ni Alaga Igbimọ awọn ọba ati Ijoye na pe ki o ma a ṣe Alaga wọn.

Irohin na tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ pe Ọlọla Adekunle Fajuyi tun yan Alaafin Ọba Ode Ọyọ Alaiyeluwa Gbadegẹ- pe ki o ma a ṣe igoasin Ladigbolu Keji, keji alakoso Igbimọ awọn ọba ati Ijoye na.



Ọlọla Adekunle Fajuyi
Gomina Ologun Iwo Orun

Lẹhin eleyi ni ọlọla Adekunle Fajuyi na tun wa yan awọn Ọba meje miran pe ki nwọn maa ṣe ọmọ Ile Igbimọ awọn ọba ati Ijoye na ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Orukọ awọn Ọba mejeje na na ni wọnyi: Alake Abẹokuta, Ọba Gbadebọ Keji, Awujalẹ Ijẹbu Ode, Sikiru Adetọna, Ọwa Ọba Ilesha, Olubadan Ọba Ibadan, Alaiyeluwa Alhaji Aminu Salawu Osemawe. Ọba Ondo Orangun Ọba Ila, Deji Ọba Akurẹ, Ewi Ọba Ado Ekiti. ati Ọba Akarigbo ọba ilu Rẹmọ.

Irohin kan ti o jade ninu Iwe Irohin Ijọba Ipinlẹ na ni ọsan ana tun ṣe alaye siwaju wi pe, Ijọba yio tun yan awọn Oloye diẹ pẹlu awọn Ọba na laipẹ lati tun jẹki awọn na wa ninu Igbimọ awọn ọba ati awọn Ijoye fun Ipinlẹ na.

Siwaju eleyi ni Ijọba Ologun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria na ti yan Igbimo kan ti yio maa mojuto akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ninu eyiti Ọga'gun na yio jẹ Olori gbogbo awọn enia ti o yan lati maa ṣe iranlọwọ fun un ni Ipinlẹ na.

Iwe Irohin Ijọba Ipinlẹ na ti o jade ni Ibadan ni ọsan ana ṣe alaye fun gbogbo awọn enia pe, Ọlọla Adekunle Fajuyi ti yan awọn enia mẹjọ, lati maa ṣe iranlowo fun un.



Ọba Moses Awolesi
Akarigbo Ijẹbu Rẹmo

Ọruko awon enia mẹjọ ti Ọlọla Adekunle Fajuyi yan sinu Igbimo na ni woọn wonyi:

Ẹniti o jẹ Olori awọn mọ [illegible] kẹta fun Orilẹ ede ilẹ Naijiria. Ọga agba fun awọn Ọlọpa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, Eniti o jẹ akọwe agba fun Ijoba Ologun Ipinle Iwọ Orun, akọwe agba ninu iṣẹ eto inawo fun Ijọba, akọwe agba ninu iṣe iṣẹ eto iṣe owo ati Iṣe Aje akọwe agba fun Mini

Wo Oju Ewe Kẹfa

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## Ọrọ Eṣẹ Ko Tọ Si Woli

Olotu/ Inn mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ lati fun Woli Kogberegbe ti o sọrọ laipẹ yi ninu iwe Irohin Imọlẹ ti o sọrọ laipẹ yi ninu iwe Irohin Imọlẹ pe "Aṣiwere ni o sọ pe Jesu ki iṣe ọ mọ Ọlọrun" ati ayiti o tun sọ ọrọ to ga ju ẹnu rẹ ju nipa pe: Bi awọn Imale ba fi ẹ m u tabi Ogogoro sinu tan lẹhin aawẹ pe awọn yio ma sọ ọrọ ti ko para.



**Wolj Kogberegbe**
'Asiwere ni ẹniti o sọ pe Jesu ki iṣe Ọmọ Ọlọrun'

Eleyi paapa ti fi han pe Woli Kogberegbe ko tẹle ilana ti Ọlọrun bikoṣe pe o kan nsọ eyiti o ba wu lati ẹnu rẹ nitoripe emi ko ti ri ninu awọn Woli to pe ara rẹ ni Ojiṣẹ Ọlọrun ti o le ma sọ ọrọ ti ko ba eti mu jade lẹnu,

Mo si tun kin Ọgbẹni R. A Dunmoye

Mo si tun kin Ọgbẹni Dunmoye lẹhin nipa ọrọ rẹ ti o sọ pe Jesu ki iṣe ọmọ Ọlọrun a t i pe mo tun fẹ tọka si fun Woli Kogberegbe pe Ọlọrun ko bimọ ati pe Mama lo bi Jesu a ko si gbọ pe Mama Iyawo Ọlọrun ni iṣe nitori eyi mo fe ki Woli Kogberegbe lọ ka Bibli rẹ daada ki o ye sọ isọkusọ eyiti lṣe ọro ẹsẹ ati pe ki o tẹle ọna ti Alufa M A Abinusawa fi gba ṣe alaye t I r ẹ fun awa Onkawe Irohin Imọlẹ gbọ.

Emi ni
Bọlaji Aina
IBADAN

## A Dupe O!

Olotu, Inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye die ninu iwe nyin ti gbogbo enia feran lati ma ka ni ojojumo lati kesi Ijoba Ologun ti ile Na'jiria labe Ogagun Aguiyi Ironsi ati lati dupe lowo Gomina Ologun Ipinle Iwo Orun Ogagun Adekunle Fajuyi fun ifokanbale ti o tun pada si ilu Iwo Orun ati agbegbe re eyiti ijoba ana eyiti Oloye Akintola ti se akoso re ko je ti o tun je bi a fe bi a ko fe a gbodo fi agbara se egbe Demonu to tu Iwo Orun ati agbegbe re si igbo patapata

Orisirisi iya ti nwon fun awa enia ilu na ti ko se egbe won eyiti nwon nlo awon afunjamaponmo gegebi janduku fun egbe Domonu lati ma bere iwe ori odun mewa lowo eniti ko ba se egbe won ati awon Wolewole ti nwon nlo bi ohun ose oloro fun awon alaise ati nipa didani duro lenu Ise

Nipa iwa bayi lo mu awon omo ilu ki o sa kuro nilu. Nipa eyi a dupe lowo Ọlọrun nitori ifokanbale ati alafia to tun pada si ilu na bayi Ope nla ni eyi pe ati kuro loko eru ijoba ologne Akintola Adura wa nipe ki emi awon Gomina Ologun wa gun fun awa mẹ kunnu nitoripe eniti a ba se lore ti ko dupe o dabi eniti olosa ko ni eru lo.

Olotu mo dupe pupo fun aye ti e gba mi ajinde ara yio ma je fun nyin ati awon isongbe nyin pelu.

Emi ni
Duro Ọyaluade
Oluponna—Iwo

## Kini O Mu E Ronu Nipa Awọn Aṣọ Rẹ ?

Bi o ba ni aṣo fun fifo tabi lilo ni aṣo bi owu (woolen) tap.ts, aṣo oke, Guluca Brocade ni ti Ọkunrin tabi ti Obinrin. A ni orişirişi aṣo ti o ba ni fun fifo tabi ti o ba fẹ yi awo ara aṣo va si miran (Changing of Colours]
*Tete Gbe Wa Si Ọdo*

**Iwajọwa Cleaner Enterprises**

87, Ọdunfa Street,
Phone 40029 Lagos

Kia ni ao ba ọ fọ, ti iwọ yio si ri gba ni ẹsẹ kanna, O le ranşẹ si wa ki a wa ko awọn aşọ rẹ na tabi ki o pe wa 'ori ẹ r ọ isọrọ (telifonu) ti nọmba rẹ wa loke lwe yi.

Bakanna ni a si tun nba enia gbọn ilẹ rẹ nu• tabi bi o si fẹ kun ile tabi ile iṣẹ rẹ, iṣọ wa tun ni yẹn na Bi enia ba si fẹ kọ ile tabi o ṣeṣẹ kọ tan o si fẹ kun o le gbe fun wa ki a ba kun, ki a si ba ṣe lọsọ ti yio jẹ oju ni gbese, A ni gbogbo iṣẹ ti o ba ti jẹ ki a t u n nkan ṣe ni o nṣe lṣẹ tiwa.

Dan wa wo lẹkanṣoṣo ki o san ri bi iṣẹ wa ti dara to.
Owo pọku ni a si ngba.

# KERE O KERE O !!

## Awọn Tani Wọnyi ?



LATI ỌWỌ OSI:- ỌNI ADELẸKAN (Olubuse) ẸNIKEJI:- ỌNI ADEMILUYI (Ajagun) ẸNIKẸTA:- ỌNI ADERẸMI (Atọbatẹle)

AWỌN ỌMỌ DUDUWA MẸTA TO JOYE 'ỌNI' TẸLE ARA WỌN

ITAN W ỌNI ILKA
Nie o ti ra ninu itan Igbesi aiye Oduduwa ati ti awon ọmọ rẹ" to ṣẹṣẹ jade?

Bi o ko ba ti ra a, maşe jafara, nitoripe, bi awo ran awọn "ỌNI" mẹta yi ti ṣe jẹ ohun iyanu la ti le ri wọ papọ, Ẹni itan wọn rẹ ninu iwe na.

Maşe ẹ ki nwọn ro hin rẹ fun o, Tete lo ra tire koto tan, 3/- pere ni, Post age 9d
F'owo tirẹ ranşẹ si:—
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria.
(Leti oja Jankara)

## Ijọba Ibilẹ Ijẹbu Igbo Jẹ Gbese Ẹgbasafa Ponun

IJẸBU: - IGBO:— Ninu Irohin kan to de ile Iṣẹ wa ni Ọjọ Aje ti Iṣe ojo kẹrinla Oṣu yi ni Irohin na ti fi ye wa pe Ijọba Ibile ti Ijẹbu ti Ijẹbu Igbo ni Igbese eyiti Iye owo rẹ jẹ egbasafa ponun (£12, 000) lati san fun Igbimọ Alakoso ete awọn Ọlọpa ti Ijọba Ibilẹ ti ẹkun Ijẹbu gẹgẹbi Owo ti o yẹ ki Ijọba Ibilẹ Ilu Ijẹbu Igbo ti san gẹgẹbi owo ti awọn ni lati san fun awọn Ọlọpa Ijọba ibilẹ fun ẹkun gbogbo Ijẹbu lo san owo na.

Irohin yi si jade lati ẹnu Alakoso Ijoba Ibilẹ fun ẹkun Ijẹbu Ọgbẹni Jacob Adebayo Ogunsanya nigba ti o ba awon enia ilu Ijẹbu Igbo nsoro ninu opin osẹ to koja lo yi

Ọgbẹni Jacob Adebayo Ogunsanya tun ṣe alaye ẹe ohun ti o fa ti ko fi si owo lowo Ijoba ibilẹ ilu Ijẹbu Igbo na ni awọn enia ilu na ti nwọn kuna lati san owo—ori wọn eyiti awọn enia ti ṣe ileri pe awọn ko ni san tẹlẹ.

Ọgbẹni Ogunsanya tun ṣe ala- ye fun awọn Ọba Ijoye ati awọn Ọmọ ilu Ijẹbu - Igbo to ti nsọrọ ni Ọjọ na pe Owo ti ko ısi laipẹ Ijọba Ibilẹ ilu Ijẹbu-Igbo yi fi mu ki Ijọba ibilẹ na kuna lati le ri Owo-Oṣu awọn Oṣiṣẹ ninu ile iṣẹ Ijoba Ibilẹ na san eyiti o fi jẹ pe Owo Oṣu ti Ijoba Ibilẹ na ti jẹ awon Oṣiṣẹ won nayi lati Oṣu mẹrin sẹhin

Ninu ipari ọrọ rẹ Ọgbẹni Ogunsanya tun rọ awọn enia ilu Ijẹbu Igbo lati tete san owo ori wọn lati le jẹki owo wa lapo Ijọ ba Ibilẹ ti ilu Ijẹbu Igbo na. Ọgbẹni Ogunsanya tun ṣe alaye fun awọn enia ilu na pe yio ṣe iwadi si iwa ti awọn Igbimo Alabẹsekele ati Ijoba Ibilẹ Ijẹ bu Igbo ti hu pẹlu awọn enia ilu na.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Lọ fi ara lelẹ, ki o siti ọkan si ọrọ aṣiri ara rẹ, nitori ire si mbẹ pẹlu rẹ nibẹ

PISCES (Fab 21 May 20) Iwọ yio ni ilọsiwaju gidi-gidi pẹlupẹlu arẹ ti o fẹ yọ ọ lẹnu, Enikan yio tun ṣe ile ri fun ọ wipe ifẹ rẹ si mbe ni ọkan en.

ARIES (May 21 April 20) Ayọ ni iwọ yio fi bẹrẹ ohun kan loni ṣugbọn nigbati o ba ya alsan yio de si ọ inu yio si ma bi ọ lori nkan rẹ ti o bajẹmaṣe bann jẹ adawodiẹni

TAURUS (April 21 May 20) Niba ọjọ ti o wa fun ọ yi, Iwọ yio ni agbara lati le yanju awọn Iṣoro to wa fun ọ ara rẹ yio si ya ko si ija larin iwọ pẹlu awọn ọrẹ rẹ, Ilọ-siwaju wa fun ọ jọjọ.

GEMENI (May 21 June 21) Lẹhinti ara rẹ gbọn diẹ fi ara mọ awọn ọrẹ rẹ, ki o si kuro lọdo awọn enia kan

CANCER (June 22 July 22) Iṣoro kan ti o farasin yio ma ṣe o ni ṣiba ṣibo, o yẹ ki o ri gbangba bi nkan ti ri iwọ yio si ri daju wipe ninu yotomi ni iwọ wa,

LEO (July 23 Aug 22) Yanju gbogbo iṣoro rẹ kuro Ki ọsan to pọn lẹhin na dubulẹ ni osan diẹ ki o wa gba tegun lo pẹlu awọn ọrẹ rẹ.

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ibinu ti o baji ni owuro yi nkan bere si ni dara bi osan ti npon, dupe fun enik n ti o ba pade ati irohin ayo kan ti o gbo, ti o mu ki Inu re ma dun

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Gbokegbodo yio po fun o ni akoko ṣugbon gbogbo re yio je Ire fun o ṣugbon nitori ohun kan ti a ko sile jeki inu baje mase binu pupo iwo yio ri ire laipe

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Lo akoko faaji re pelu awon ofufe re to la lo lo se abewo awon enia awon elo miran yio fe lati gbo oro lenu re oro owo kan yio dija sile

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Ko si isoro kan ni osan re ti o se pataki loni ṣugbon ki o lo dubule ki o sun tabi ki o lo mu faaji pelu awon ore re

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Ọjọ oni le koko bi oju eja o yo ki o din ise re ku die ki o si ma se anu fun awon enia


# Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Airi iṣẹ se ha wa fun ọ bi ?
Ailern mba ọ ja bi

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wonyi ti iwo ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ti a to lesẹsẹ si Isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọsẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Aj bidan 4/6 di 3/6
3 Iwe Itumọ Ala ati Ogun Wibẹjẹbẹ 4/6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awọ ba Arun 20/— di 17/6
5 Iwe Ilana Ifa Yoruba tite ati etutu ṣiṣe 20/- di 17/6
6 Gbedegbẹyọ Hausa 3/—
7 Iwe Aniyan Irun 2/— di 1/—
8 Turari Iṣegun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paket

Fi Owo ranṣe si
J, O, SHOYINKA
P, O, Box 159
MUSHIN
tabi
9, Iyala Street Oduaborẹ, Mushin




# KERE O

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA ose ṣejade ?

Ha ! Kosemani ni Iwe na je fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan Iṣẹdalẹ Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Mase jeki nwon rohin itan ilu rẹ fun ọ
3/- pere ni. Postage 9d

Tete fowo tirẹ ranse si:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

# Aṣọbade Orire Are Bọọlu

## Division 1

| | |
|---|---|
| Aston Villa v Black- urn | x |
| Burnley v Everton | 1 |
| Chelsea v Arsenal | x |
| Liverpool v Blackpool | 1 |
| Northampton v Newcastle | x |
| Notts F v Leeds | 2 |
| Sheffield Wed v West Brom | 1 |
| Stoke v Man Utd | 2 |
| Sunderland v Leicester | 2 |
| Tottenham v Fulham | 1 |
| West Ham v Sheffield U | x |

## Division 11

| | |
|---|---|
| Bury v Southampton | 2 |
| Charlton v Birmingham | 2 |
| C Palace v Middlesbro' | 1 |
| Man C v Coventry | x |
| Norwich v Derby | x |
| Plymouth v Ipswich | x |
| Portsmouth v Bolton | x |
| Preston v Leyton O | x |
| Rotherham v Carlisle | 1 |
| Wolves v Cardiff | 1 |
| Huddersfield v Bristol C | 2 |

## Division III

| | |
|---|---|
| Bournemouth v Gill'gham | 2 |
| Brighton v Reading | 1 |
| Bristol R v Mansfield | x |
| Oldham v Millwall | 2 |
| Oxford v Grimsby | 2 |
| Q.P.R. v Hull | x |
| Scunthorpe v Exeter | x |
| Swansea v Shrewsbury | x |
| Wallsall v Swindon | 2 |
| Watford v Peterborough | x |
| Workington v Southend | 1 |
| York v Brentford | 2 |

## Division IV

| | |
|---|---|
| Aldershot v Barrow | x |
| Bradford v Hartlepools | 1 |
| Chesterfield v Barnsley | 1 |
| Colchester v Bradford C | 1 |
| Darlingt on v Halifax | 1 |
| Lincoln v Chester | x |
| Southport v Notts Co | 2 |
| Torquay v Rochdale | 1 |
| Wrexham v Doncaster | 2 |

## Scottish Div 1

| | |
|---|---|
| Aberdeen v Clyde | x |
| Celtic v Dundee | 1 |
| Dundee U v Rangers | x |
| Falkirk v St Johnstone | 1 |
| Hibernian v St Mirren | 1 |

### Treble Chance (12 draws)

Aston Villa, Chelsea, Northampton, West Ham, Man City, Norwich, Plymouth, Portsmouth, Preston Bristol Rovers, QPR Watford

### Four Aways (8)

Man Utd, Leeds, Southampton, Birmingham, Bristol City, Millwall, Brentford, Doncaster

### Nine Homes 15

Burnley, Liverpool, Sheffield Wed, Tottenham, Crystal Palace, Rotherham Wolves, Brighton, Workinston, Bradford Chesterfield Colchester, Darlington Torquay, Lincoln.

### Three draws 6

Chelsea, Man City, Norwich, Portsmouth, Watford QPR.


BERE FUN OJULOWO EGBOGI—

## "Congreve's Iodo From—Oinment



Atamataṣe ni egbogi" ADIELEGBO" yi j· fun itọju gbogbo orişirişi "EGBO—ẸSẸ" ni kiakia bi o ti wu ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹri gbogbo ti ba wa loju egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo yi o ba jin sinu yio jeki oju re hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko si mọ werewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ niyen !—

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won absale iwe yi ni ogbe ranşe lọ r.. Bibeko awon Elerẹ ihli on ijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maşe gba rarao

Waterloo Medecine Stores
8, Palm Church Street P O Box 333 Lagos



## Ila Kini Meyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLỌRI ERIN MẸTA

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara jul gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun,

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ yio ri bi o tişe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ 'yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu, ori erin mẹta ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣobu lo itaja kakiri Oriiẹ ede yi

Distributor
AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemọ Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West



a successful future means planning **Now!**

Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW

with

**GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,**
INCORPORATED IN NIGERIA

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE:

39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2014, LAGOS
TELEPHONE 25541.

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,701 FRIDAY, FEBRUARY 18 1966 (2D)


## Oshuntokun F'ara Han Ni Tesan Olopa

IBADAN:— Ni Ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Minista Alamojuto eto ẹkọ fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tẹlẹ ri Oloye J. O Ọshuntokun ati Ọgbẹni Adetoye Adeyinku ọkan ninu awọn Igbimọ Alakoso ile iṣẹ Onisowo fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ lọ si ọlu iṣẹ awọn Ọlọpa – nu ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni Ibadan ati pe awọn enia meji na si lo Ọpọlọpọ wakati ni Tẹsan awọn Olọpa-nu ni ọjọ na.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe ọkan ninu awọn Minista fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ Ogbẹni A. B Bello tun fara han ni Tẹsan awọn Olọpa ni Ibadan ni ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun Oṣu yiwa.

Oniwe irohin ni ilu Ibadan fi ye wa pe bakanna ni awọn enia mẹta yi ti nwọn jẹ ọkan ninu Olori ẹgbẹ Demọ fara han ni Tẹsan awọn Olọpa-nu na ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni ọsan ọjọ na eyiti irohin fi ye wa pe nwọn ko mọ ohunti awọn enia ijijọ sọ pelu awọn Ọlọpa-nu.

Oniwe irohin wa fi ye pe awọn enia yio pẹlu awọn Olori ẹgbẹ Demọ kan ti awon Ọlọpa-nu ti nfi ọrọ wa lẹnu lati igba yi.

Irohin fi ye wa pe Oloye J. O Oshnutokun wọ aṣọ penpe kan ti nwọn npe ni Shirt pẹlu Ṣokoto gigun dudu kan bayi ati pe ori aga kan lo si juko si ni Tẹsan awọn Ọlọpa – nu na ni Ibadan.

# GBỌMỌGBỌMỌ KAN JI OMO ODUN MEJI GBE

PỌTA:— Kẹkẹ pa ohun mọ awoko lẹnu nigbati awọn Ọlọpa mu ọdaran kan, Robinson Amachree, eni ọdun mẹrinlelogoji wa siwaju adajo ile ẹjọ giga fun ẹsun ajọmọgbe ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na sẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ wipe, awọn ọmọde mẹrin kan nṣire niwaju ile wọn ni King Jaja Street Pọta ni ọdaran na si gbe ọkan ninu awọn ọmọde na, Selina Ayigbama Kwanari, eni ọdun meji.

Ṣugbọn bi ọdaran na ti gbe ọmọ na tan, o gbe lori basikulu kan, ti osi ngbe ọmọ na salọ; ṣugbọn nigba ti o de ilu kan ti nwọn npe ni Okirika, ni awọn Ọlọpa ri ọdaran na, ti nwọn si bere ibiti o gbe ti ri ọmọ ti o gbe lori Basikulu ati oruko ọmọ na.

Nigbati awọn Ọlọpa ti da ọdaran na duro, ni o ti ngbọn titi bi igbati Alupupu ti o baje ba fẹ gun ori oke, ti ko si tun le so ibiti o ti ri ọmọ na ati orukọ ọmọ na fun awọn Ọlọpa ti nwọn nbere lọwọ rẹ.

Nigbati awọn Ọlọpa ṣe akiyesi bi ọderan na ti ṣe nṣe, ni nwọn ba fura si ọdaran na wipe on ko lo ni omo ti o gbe si ori basikulu nwen si mu lo si Tẹṣan awọn Ọlọpa.

Nigbati nwon yio fi de Teṣan ni nwon ti ba awon Obi omo na ti nwon nwa omo won kakiri pe awon ko ri omo awon mo nibiti on ati awon ẹlẹgbẹ rẹ gbe jijọ nṣire.

Ṣugbọn awọn Ọlọpa ti omo na yo ni okere ni won Obi omo na ti so wipe omo ti awon nwa kakiri na niyi omo won ni nwon ti gbe de yi.

Ọlọpa na tun ṣe alaye pe nigbati awọn ọlọpa mu ọdaran na de Tesan ni awọn to mọ pe ọdaran na sa jade kuro ni ọgba ewon ni, nito ripe ọdaran na si nṣe ọdun meji lọwọ

Ṣugbọn o sa jade ni ọgba ewọn nigbati ko ti ṣe ẹwọn na tan awọn ọlọpa si ti tun nwa ọdaran na kakiri lati igbati o ti sa jade kuro ni ọgba ẹwọn

Nigbati ọlọpa na soro tan ni adajo wa bi odaran ajomogbe na lere ohunti o fẹ so lori awon ẹsun mejeji ti awon olopa mu wa si ile ẹjo fun

Lẹhin eyi ni odaran na rojo ṣugbon ni opin ẹjo rẹ, o gba pe ni otito ni on ji omode na gbe bẹẹni on si tun ṣẹṣẹ sa jade kuro ni ọgba ẹwon ni.

Nigbati odaran na rojo tan, ti o si gba wipe on jẹbi ẹsun na, ni adajo ba ṣe idajo pe ki o lo fi ẹwon odun meje jura pẹlu ẹwon odun meji ti odaran na ti nlo lo tẹlẹ ki o to sa jade.

# DẸMỌ FỌ

## Lati Oju Ewe Kini

ta Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ ati Oye jijẹ.

Akọwe agba ninu ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Ofin ati Idajọ akọwe agba ninu ile iṣẹ Minista Alamojuto eto Iṣẹ Ojumọ ati iṣẹ Ida silẹ fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

Oniwe Irohin wa kan ran wa leti wipe, Ọlọla Adesọji Aderẹm, Ọni Ọba Ile—Ifẹ ti kọkọ wa ni Alaga Ile Igbimọ awọn ati Ijoye ni Ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ ri ki nwọn to yọ kuro nibẹ nigbati Oloye Akintola fi di Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ninu ọdun 1962.

Nigbati nwọn yọ Ọba Ọni yi kuro ni ori oye na tan ni nwọn tun wa yan Ọlagbegi Ọlọwọ Ọba Ọwọ ni Alaga Ile Igbimọ awọn Ọba ati Ijoye fun Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria.

Ṣugbọn nisisiyi ti Ijọba Ologun gba akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ na yi, Ọlọla Adekunle Fajuyi eniti ise Gomina Ologun Ipinlẹ na nisisiyi ti tun yan Ọlọla Adesoji Aderẹmi Ọba Ọọni Ile—Ifẹ ni Alaga Igbimọ awọn Ọba fun Ipinlẹ na.

Nigba ase ti Gomina na pa ni Ibadan ni ọsan ana Gomina na tun sọ pe bi ọba Ifẹ ba jẹ Alaga Igbimọ awọn ọba ni Ipinlẹ na ki Alaiyeluwa Ọba Gbadegẹ sin Ladigbolu Keji ki o ṣe Igbakeji rẹ ninu ile Igbimọ Ọba ati Ijoye na.

Oniwe irohin wa ni Ibadan fi ye wa wipe gbogbo awọn enia ni nwọn bẹrẹsi ma jo kakiri gbogbo ilu Ibadan ni ana nigbati nwọn gbọ Irohin ti Gomina na fi yan awọn Ọba wọnyi si oye wọn.

Onirohin wa sọ pe nigba ti on gbọ irohin na on sare lọ si Ile Alaiyelawa Adesoji Aderẹmi Ọọni Ọba Ifẹ ni Ibadan ni ana ṣugbọn awọn enia ti on ba nile sọ fun on pe ọba na wa ni Ile Ifẹ lati nkan bi ọsẹ meji lo ti lọ si Ile—Ifẹ.

Oniwe Irohin wa fẹ lo be re oro diẹ nipa aye tuntun ti Gomina na ṣẹṣẹ yan ọba Olokiki na si, ati ki o si tun gbo ohunti Ọba na yio sọ nipa aye rẹ tuntun ti Ijọba tun yan an si yi.

Nigbayowu ti Oniwe Irohin wa ba si ri Ọba na, oh nti o ba wi, ẹ o maa gbo:

A tun lero lati de odo gbogbo awon enia ti Ijoba Ologun yan si awon aye tuntun wonyi, ki a si gbo ero won nipa aye ti Ijoba ṣẹṣẹ yan awon Ọba na si yi.


Printed and Published By Modupe Printin Press 16, gose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADBOSUN 25 Branco Street Lagos 18/2/66